**Lakaye Ọrọ**

ENITI o ba gba mi gbọ o gba Baba mi ti mbe l'orun gbọ. Ẹ o si mọ otitọ, otitọ yio si sọ nyin di ominira.

# Irohin Yoruba

No. 820 FEBRUARY 22 — FEBRUARY 28, 1961 KOBO MEJI (2D)

**OWE**

Orịṣa bi o ko le gbe mi, kuku ṣe mi bi o ti ba mi.

# AWỌN ẸBI FI AAKE K'ỌRI NIPA ỌRỌ OYE OLUWA EKO

## NWỌN NI AWỌN KO F'ARAMỌ ẸNITI ADELE DE FILA FUN

LATI igbati Ọba Alaiyeluwa Adeniji Adele Keji, Ọba Eko, ti fi ọwọ si pe Ogbẹni Abudu Rashidi Akande Akibọ ti apele orukọ rẹ nje "Afuwapẹ," ni ki o jẹ oye Oluwa Eko. ni rogbodiyan ti o wa larin awọn koko ninu ẹbi Oluwa ati Ọba na. Nwọn fa ọrọ na lọ siwaju, nwọn fa a lọ sehin, ṣugbọn ni ikẹhin, Ogbẹni Akibọ jẹ oye na ni ọjọ [illegible] ti iṣe ọjọ kejila [illegible] yi ni Iga Olumẹgbọn.

Nigbati nwọn si ṣe eto ifinijoye tan ni Iga Olumẹgbọn ni nwọn wa ṣe eto yoku ni Ẹnu Ọwa.

Ṣugbọn pẹlu bi Ọba ti ṣe yi, awọn ẹbi idile Oluwa ṣi fi aake kọri, nwọn ni awọn ko fi ara mọ ẹniti Ọba fi jẹ oye na. Nwọn ni Ogbẹni Abudu Karimu Balogun ni awọn yan, on si ni awọn ti panupọ mu ni oloye titun. Lati bi ọsu mẹta ti awọn ẹbi yi ti wa lẹnu ọran oye na ni ariwo ati okiki ti nkan kakiri ilu Eko.

Okiki na pọ tobẹẹ gẹ ẹ ti Ọba Adele fi ṣe iwadi nipa tani o kan lati jẹ oye na, ṣugbọn nigbati o gbe ayọrisi iwadi rẹ jade, awọn ẹbi idile Oluwa tun fi aake kọri, nwọn sọ pe Ọba ko ṣe ẹtọ nipa ọrọ na rara. Nwọn ni "ẹnikan kole mọ iya Ọṣọ ju Ọṣọ lọ," nwọn ni awọn lo mọ nipa idile wọn, nitorina, nwọn ni awọn ko gba nkan ti Ọba fẹ ṣe fun awọn.

Alaye ti ọpọlọpọ ninu awọn ọmọ oye tun ṣe nipe awọn ni awọn ni ẹtọ lati yan ẹniti awọn ba rii pe o tọ lati jẹ oye Oluwa si ile baba awọn. lẹhin ti awọn ba si ti mu ẹniti awọn ba rii pe on ni oye na ba tọ si, ni awọn yio nilati ṣẹṣẹ wa sọ fun Ọba gẹgẹbi asa ìṣẹdalẹ ilu Eko.

Ninu alaye wọn na, awọn ẹbi sọ pe lehin ti baba Ogbẹni Abudu Rashi-

(Wo oju ewe kẹrindilogun)

* * *





Aworan oke akọkọ yi ni ti igbati nwọn nfi Ogbẹni Abudu Rashidi Akibọ jẹ oye Oluwa, ti nwọn si mu u wa si Ẹnu Ọwa lati wa kan. Aworan keji ni ti igbati Ọba Adele wa si Minna, Ogbẹni Karimu Balogun ti o ṣẹṣẹ lalejo lewa nibi kẹrin niwaju yi.

# Gomina Ipinlẹ Iwọ-Orun ni a ko gbọdọ joko tara-tara nitoripe ominira ti de

OGBOMOṢHỌ.

OLỌLA Ọba Alaiyeluwa Adesoji Aderẹmi Gomina Ipinlẹ Iwọ-Orun bẹ awọn aṣiwaju oṣelu Naijiria pe ki nwọn ri i pe nwọn ṣiṣẹ dada fun igbega Naijiria ati fun irọrun ati alafia ninu ominira to bẹẹ gẹẹ ti awọn mẹkunnu yio fi fi idunnu ki wọn ku'ṣẹ. O ṣe ẹbẹ yi nigbati o lọ bẹ ilu Ogbomoṣhọ wo ti o si mba awọn Igbimọ Ijọba Ibilẹ ilu na sọrọ.

Gomina na si ṣe alaye ninu ọrọ iwuri rẹ pe "a ko gbọdọ joko tara-tara nitoripe a ti gba ominira, ṣugbọn a gbọdọ sa gbogbo agbara wa lati ṣegun gbogbo awọn ohun ti o le di wa lọwọ lati tubọ jẹ'gbadun aiye ju eyiti a ti njẹ bọ nigbati a ko i ti i gba ominira."

O ni ọpọlọpọ wa ni a si nfi ibajẹ ṣ'ayọ, ti a si wa ninu okunkun. Nipa bayi a ngbe inu ẹrẹ, a ko si ni anfani Dọkita fun itọju ara wa to.

Ọlọla Gomina na kansaara si Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun nitori iṣẹ ribiribi ti Ijọba na nṣe fun igbega ati anfani awọn ara Ipinlẹ na. O ni Ijọba ti da ọpọlọpọ iṣẹ ajẹẹjẹ 'tan silẹ fun ara ilu ti yio mu igbesi-aiye wọn rọrun gan an, o si yin Oloye S. L. Akintọla, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun na pupọ fun oye aapọn, itẹramọṣẹ ati lakaye ati otitọ rẹ nigbagbogbo.

Bi Ọlọla Gomina na ti ngunlẹ si Ogbomoṣhọ ni ọjọ na ti o lọ bẹ ibẹ wo ni awọn ara ilu na gba a lalejo t'ere-t'ayọ, nwọn si fun un ni iwe-ayẹsi ikini-ku-abọ. Nwọn sọ sinu iwe na bi awọn ti ṣe gbadun iṣẹ ti Gamina na nṣe fun anfani Naijiria, ati bi o ti ṣe nfi gbogbo agbara rẹ ja ija lọna ẹtọ lati ri i pe Naijiria di ominira. Nwọn ni laisi-ani-ani, awokọṣẹ enia gidi ni Gomina na.

Nigbati o di ọsan ọjọ na, Oloye Akintọla, ṣe aseapejẹ nla fun Gomina na ni ile rẹ, nwọn si jijọ ṣọwọpọ. Lẹhin eyi, ni Gomina na si lọ si Oshogbo gẹgẹbi eto irin-ajo rẹ.

**Ẹ ma a ka Iwe**

**IROHIN YORUBA**

**nigbagbogbo fun irohin aladun**






## ỌRỌ AKEWI : Lati ọwọ ỌMỌ-ỌBA AKIBU ALARAPE, IBADAN

# ALUBARIKA LOJU (6)

OLOTU Iwe "Irohin Yoruba," E nlẹ loni o, kara o le o. Ni kukuru, ṣe ibiti ọrọ wa na de ni ọsẹ ti o koja ni wipe iyawo na si mbere lọwọ ọkọ rẹ wipe, nṣe ni ki ọkọ on sọ iru nkan ti owo yi ba le to fi ra fun on nitoripe "owo na ko tilẹ le to fi ra nkan ọbẹ rara, ki a to ṣẹṣẹ sọ nipa ti ọbẹ na paapa ti a nfẹ se fun onje wa loni."

Ogboni na si tun sọ fun iyawo rẹ wipe, "iwọn nkan ti owo na ba le ra ko buru, ṣugbọn nkan ti mo ro wipe o ṣi dara ni wipe, ki a sa tilẹ se ọbẹ loni, bayowu ki o le mọ. Nitorina, emi papa yio lọ sinu ọgba mi nisisiyi lati lọ re e tọju nkan diẹdiẹ ti a ba le ri fi se ọbẹ na wa silẹ.

Tabi ko dara bẹ e? Nigbati o jẹwipe oriṣiriṣi nkan ọbẹ ni o wa ninu ọgba wa ni isalẹ odo. Atipe, mo tilẹ ṣe akiyesi ni ijẹta ti mo rin lọ sinu ọgba na wipe awọn bara ti a gbin si apakan ọgba na ti gbo daradara nisisiyi fun ẹgusi."

Iyawo na si dahun wipe "ko buru."

Bayi ni awọn mejeji jade ninu ile, ti iyawo si gba ọna ọja lọ, ti ọkọ na si kọri sinu ọgba. Nigbati ọkọ iyawo de inu ọgba, o ṣe igi diẹ lati wa fi dana nile o si tun tọju nkan bi ata, ẹfọ ati bara-ẹgusi nlanla mẹrin ti o ti gbo daradara.

Ogboni na si dari wa sile lati ma a reti iyawo rẹ. Ko pẹ pupọ lẹhin eyi ni iyawo na wọle de pẹlu ẹja nla kan ti o ra bọ pẹlu awọn eelo ọbẹ miran pẹẹpẹẹpẹ. Iyawo na bọ si idi aaro lati ma a dana, ọkọ na si bọ si ẹhinkule lati ma a pa bara wonyi.

Bi Ogboni na ti gbe ọbẹ le ọkan ninu bara wọnyi ti o si la a si meji pere, bẹni imọlẹ nla kan la gbo o, to bẹ e ti ẹru fi ba Ogboni yi, o si kesi iyawo rẹ lati wa wo nkan ti a ṣelẹ. Eyi jẹ iyalẹnu nla fun iyawo paapa, ṣugbọn lẹhin iṣẹju diẹ ,ọrọ na wa han si wọn gbangba wipe, kiki ALU-ULU (Diamond) ni o kun inu bara na, eyi si jẹ iyalẹnu ti ko ni apejuwe fun tọkọ taya na, to be e ti awọn mejeji ko fi le la ẹnu sọ ohunkohun, nṣe ni nwọn sa nwo ara wọn loju pẹlu idunu nla ti ko se e rohin.

Laipẹ, awọn mejeji si mi kanlẹ hun un, nwọn ni, "a ma dupẹ ore nla yi o, Ẹlẹda wa!" Lẹhin na ni



AKIBU ALARAPE

* * *

nwọn palẹ nkan wọnyi mọ kuro nilẹ. Ṣugbọn sibẹsibẹ na, nṣe ni awon mejeji sa nkosile ti nwọn nkosode pẹlu ayọ nla, to bẹ ẹ ti nwọn ko tilẹ mọ ohunkohun ti nwọn tun le se mọ titi ti o fi di ogun wipe Iṣasun ọbẹ ti iyawo gbe kana fi bẹrẹsi jona.

Lẹhin eyi ni iyawo na ba sure lọ si idi aaro lati lọ sọ ọbẹ na kalẹ lati tubọ se amojuto ọbẹ na dada. Bi iyawo na ti kọja si idi aaro bẹ ẹ na ni ọkọ rẹ si tun koja si ẹhinkule lati lọ ru bara mẹtẹta yoku danu.

Ṣugbọn lẹsẹkẹsẹ ni ero na wa si ọkan rẹ wipe "kiniṣe ti ngko fi pa bara yoku yi lati le mọ nkan ti o wa ninu wọn?" Bayi ni Ogboni yi bẹrẹsi pa awọn bara wọnyi lọkọọkan; pẹlu iyalẹnu nla ni nkan na si jẹ lati ri i wipe, kiki ALU-ULUU (Diamond) ni o wa ninu ọkọọkan.

Laiṣe ẹmi ọrọ ni gigun, bayi ni Ogboni yi pẹlu iyawo rẹ ri i wipe, dajudaju, awọn ti di ọlọla enia nipa ọpọlọpọ alu-uluu yi, nwọn si ṣe itọju awọn nkan na daradara.

**AYỌ NLA DE**

Ayọ nla si ti gba ọkan awọn mejeji na kan to bẹ ẹ ti iyawo paapa tilẹ ti gbagbe ọbẹ ti o wa lori ina patapata. Ṣugbọn laipẹ, Ogboni yi sọ fun iyawo rẹ wipe, ko daju wipe awa yio le se ọbẹ mọ loni, nitorina, kuku lọ mu ẹja ti a fẹ fi se ọbẹ wa ki a ya jẹ bẹ ẹ bẹ ẹ, ki a si mumi si i, bi o ba di ọla ki a se ọbẹ pẹlu ifọkanbalẹ.

Iyawo na si gba bẹ ẹ, o si lọ mu ẹja na wa. Bi Ogboni na si ti fa ẹja na ya si meji, nṣe ni ọpọlọpọ alu-uluu miran tun gbon wẹẹrẹwẹ dasilẹ ninu ẹja na, ti gbogbo ilẹ si kun rẹpẹtẹ fun alu-uluu.

Eyi wa kọja ti ayọ nikan fun awọn tọkọ-taya na, iberu diẹdiẹ wa bẹrẹsi bọ si ọkan wọn nipa eyi. To bẹ ẹ, ti o fi jẹwipe, funra ara iyawo na ni o wa bi ọkọ rẹ lere wipe, "njẹ nkan wọnyi ko ṣẹ npọju bayi? Tabi ewo ni ṣiṣe o, baale wa?"

Olotu, ki a tun fi rere pade o. Ọmọ-Ọba nrele o. O digba.



# Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ṣi ile iwe fun awọn ọmọ alaigbọran



LENULOLOYI ni Oloye J. O. Oshutokun Minista Alamojuto Eto Ilera ati ti Oran Arin Ilu si Ile Iwe awọn ọmọ alaigbọran ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ko si Abẹokuta lati ma a ko awọn ọmọ iganna ati alarinkiri ni ẹko ki nwọn ba a le jẹ enia atata lẹhin ọla.

Iye owo ti nwọn fi pari Ile Iwe awọn ọmọ alaigbọran na jẹ egbaawa pọun (£20,000)

Ninu awọn enia ja-nkan ja-nkan to wa sibi iṣile na ni awọn ọba Alaiyeluwa Adeṣina Olubara Ibara, Ademọla Ọshilẹ Oke-Ọna ati awọn Ijoye nla-nla ni Abẹokuta.

Aworan oke yi niti ile iwe na.

## Ẹgbẹ Shaki Parapọ ni Ghana ṣe ipade alarinrin

BOLGATANGA, Ghana. IROHIN ko to afọjuba ni ti aṣeyẹ ipade nla ti awọn ọmọ Ẹgbẹ Shaki Parapọ ṣe ni ọjọ Ilu ti l ṣe ọjọ kẹjidinlogun oṣu kinni ọdun yi. Ninu ipade na ni nwọn yan awọn aṣoju sinu igbimọ ẹgbẹ na.

Awọn aṣoju na ni wọnyi: Ọgbẹni Yesufu Ladokun (Yendi), Busari Akano (Kete krachi), Fasasi Agbongbo (Tamale), Salawu Giwa Olowolagba-Lana (Kara), Lawani Aderogba (Bawku), Gbadamosi Ayinde (Accra), Busari Akee (Bolgatanga), Alhaji Mustafa (Nondom), Raji Giwa (Wa), Ashiru Adegbọla (Wulensh), Yesufu Iroko (Bimbilla), Shittu Adesokan, Alfa Sadiku (Komonaba).

Ninu ipade na nwọn tun yan awọn alamojuto. Awọn na ni ọgbẹni Salawu Dogo, (Lamakara), Salawu Ọrẹdẹgbẹ (Djereponi), Shittu Ore (Sokogun).

Awọn igi lẹhin ọgba Ẹgbẹ Shaki Parapọ na ni Ọgbẹni ; Bab-Mustafa (alaga), Adetoro (Tamale) Baba Saidu (Shaki), Alhaji Aileru Giwa (Shaki), Salawu Oba Yomba (Bolga), Alhaji Agbada Kelli (Shaki), Ashiru Baba Ape (Napari Tatale), Baba Alli Giwa (Bolga).

Alaga ipade na ni Ọgbẹni Gbadamosi "Big Man" (Tamale), Akọwe ni Ọgbẹni A. A. Y. Ọrẹdẹgbẹ, on na si ni o jẹ agbowo Mọṣalaṣi Shaki ni Bolgatanga.

Gbogbo awọn akọwe igbimọ ẹgbẹ na ni awọn Ọgbẹni Fasasi Bada, Sunmọnu Alade, Lawani Adegoke, Muritala Lawani (Kutọnu) Raimi Lasisi Ọlaniyi ati ọpọlọpọ ti ko si aye fun lati darukọ wọn sinu iwe yi.

Ipanupọ ẹgbẹ na ni pe ni ọdun to mbọ nwọn yio ṣe ipade nla ni ilu Shaki. Nwọn si fi ọjọ ipade na si ọjọ kejila oṣu kinni ọdun 1962.

## Akiyesi fun ala-ala

**Eyi ni lati sọ fun ẹnyin ti ẹ ti fi ala ṣọwọ si Josefu Alala pe ki o tumọ ala fun nyin ti itumọ na ko si ti i jade, pe bi ẹ ba fẹ ki o jade ki ẹ fi ṣile meji-abọ (2s:6d) ṣọwọ, yio si tete jade. A si fẹ sọ fun nyin pe, itumọ ala nikan ni Josefu Alala ntumọ, ki i ta iwe ala rara o.**

**OLOTU.**



# Classified

BI a ti ṣọwọ kọ awọn irohin ti o wa ni isalẹ yi ni a o ma a kọ awọn irohin ti a ba ri gba ti awọn enia ti o ba si fi ṣọwọ si wa ba fi owo titẹjade ṣọwọ pẹlu gẹgẹbi akiyesi ti a tẹ jade ninu iwe "Irohin Yoruba" ọsẹ ti o kọja. Nitorina a bẹ gbogbo ẹnyin onkawe wa lati tẹle apẹrẹ na gẹgẹbi akiyesi ti a ṣe na.

OLOTU

* * *

IKỌTUN-ỌFFA

OGBẸNI Sunmọnu Akano ko ọmọkunrin ti Ọlọrun fun on ati aya rẹ, Ọmọmeji Ajokẹ lorẹ jade ni ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kerindinlogun oṣu kini ọdun yi. Alfa Yusufu Ọmọyeni ni o ṣe isin isọmọloruko. Ẹsẹ awọn oriṣiriṣi ẹgbẹ ati awọn gbajumọ ni o pe si ibi aṣeyẹ na.

* * *

OGBẸNI Johnson Ade Fashola ṣe ikomọ ọmọ ọkunrin ti Ọlọrun fi ta on ati aya rẹ lorẹ, lẹnuloloyi Nwon sọ ọmọ na ni Oluwọle Aderẹmi Ọlayi-




# Advertisements

...ika. Ogbeni Moses ...ahunsi ni o si se isin ...omoloruko. Awon Ogbeni ...ichael Oyinlola, Magnus ...amoye, Nicholas Ayan...de, Omo-Oba G. Popoola ...i awon omo Egbebirin ...".W.C.A." wa ninu awon ...abaseye ojo na.

* * *

ILORIN

...I ojo Aiku ti ise ojo kejilelogun osu kini ...un yi ni Ogbeni Michael ...olani alagbede wura gbe ...nidan Abike Obadogun ... iyawo.

Ni kete ti won jade ni ile ...in ni ese awon alabaseye ti pe si ile oko iyawo na nibi ti won ti ñ jije ati mimu te opolopo enia lorun ti gbogbo won si ñ ijo p'eta.

* * *

GABASIN

LENULOLOYI ni Olorun ñ ibeta (eta-oko) ta Malama Ajiji ati oko re Malam Aji, Baale Gabasin ni Wukari lore. Ni Ile-Igbebi Ijoba ni nwon gbe bi awon omo na si. Alafia si ni iya ati awon omo meteta na wa. Lati igbati nwon si ti bi won ni opolopo enia ti ntowo wa ki won ku orire.

## AKIYESI PATAKI

Ki ifokanbale le wa fun eniti o ba ñ iwe irohin ikomojade, isinku, igbeyawo, isile ati bebee lo sowo siwa pe ki o jade ninu Iwe Irohin Yoruba. Bi o ba fe ki o jade ni oranyan ki o kuku se ni ipolowo oja, sile kan abo (1/6d) ni a ngba fun oro marun fun apere:— "Irohin koto afojuba ni aseye oku iya Moradeyo ti o se l'ojo kewa osu yi". Eyi je oro medogun, owo re si je sile kookanabo ona meta o je sile merinabo (4/6). Bi o ba si ti po to ni owo re yio ñ po to. Oro marun fun sile kan abo (1/6) nt.

**OLOTU**



# DA
# INU-RIRUN DURO

Nigbati o ba ni irora ninu ikun re, ohun ti o nfa idi re nigbagbogbo ni pe omiro ti poju nibe. Omiro yi ni o nfa arun-inu, inu-kikan-ni ati airi-igbe-ya.
Sa ti mu egbogi Phillip's 'Milk-of Magnesia' die .........yio si ko rirogun omiro na kuro, a si le irora na lo werewere. Yio fun okun-inu lagbara lati ti gbogbo nkan ti o nfa irora na jade kuro lara.
Ko lewu, o rorun lati lo, o si tu ni lara.

**'MILK OF MAGNESIA'**

Awon ti o nse e ni

**PHILLIPS**




ODARA FUN GBOGBO EBI

# Eni-owo Samuel Ade. Atiba je oye ni Soosi Mushin



ESE awon ebi ati ore Eni-owo Samuel Adewunmi Abati lo pe sibi isin ifinijoye ti nwon se ni ojo Aiku, ti i se ojo kejila osu yi ni Soosi Ebenezer ti Enia-dudu ni Mushin. Irohin ko to afojuba ni ti aseye ojo na.

Eni-owo Bisopu E. A. Macaulay olori ijo soosi na lo se eto isin ojo na. Eni-Owo C. E. A. Lawson si ran an lowo. Eto isin na bere pelu orin lehin na ni nwon gba adura, nwon si tun korin. Nigbati nwon se eyi tan ni Bisopu Macaulay wa beresi so oro iyanju. O ki awon ebi ati ore Ogbeni Abati pupo pe nwon ku orire ti oye soosi ti eni won je, o si kan saara si Eni-owo Abati paapa fun oye ile Oluwa ti nwon ngbe kaa lori lojo na. Bisopu na tun gba Eni-Owo Abati ni iyanju pe ki o tera mo ise rere lati 'maa se, o si se adura fun un gidigidi.

Lehin eyi ni awon ijo soosi na tun korin ikan, ninu nwon nkorin yi lowo ni nwon lo mura oye fun Eni-Owo Abati, nigbati nwon si mura fun un tan ni nwon ba tun mu u wa si aye re ninu soosi.

Eto isin ojo na pari pelu adura lati odo Bisopu Macaulay.

Lehin isin ogunlogo enia ba Eni-Owo Samuel Adewunmi Abati lo si ile re ni opopo Ojo ni Mushin, ibe ni nwon si tun gbadura fun un.

Awon ti aye wa fun lati daruko ninu awon to wa sibi aseye ojo na ni Eni-Owo T. A. Abati, ti ise olori ijo "St. Michael's Church" Mushin, ti o si je baba oloye titun yi, Ogbeni C. A. Buko, J. A. Ogunfowokan, S. E. Obajinmi, George Lawani, Popoola Adegun (Yes I Know), Adekunle Abati, George I. Oyekan, awon Iyaafin Abiodun Ademorin, Christiana Adeniji, J. Ade, Bambey (Olude), Grace Aina, Adedoja Abati, Adenike Abati, Taiwo Abati, Victoria Yetunde Awolesi ati Omidan Adeyinka Abati.

Aworan oke yi ni ti igbati Bisopu Macaulay ngba adura fun Eni-Owo Abati. Eni-Owo Lawson lo duro ti won legbe otun yi.

## Ijoba pa ise Ligali re

APAPO Ijoba Naijiria tu ibise "Ligali Commercial Syndicate" ka lenuloloyi Okowo ise na le ni egberun ponun (£1,000). Alabojuto ise na ni Ogbeni Abdul Raheem Ligali ti o ngbe 59, Ojo Giwa Street l'Eko to si nse ewon lowo lati fi tanran ejo ole ti ijoba ba a se ti o si jebi re.

Gegebi ofin, egbe onisowo ti ko ba lo se eto irufe aye agbara owo ti egbe won na wa ni arin odun kan fun Ijoba, Ijoba yio pa egbe na re. Egbe "Ligali Commercial Syndicate" si ru ofin yi, ko lo se eto na.

# Akede Ọna Igbala

## "KINI O KU MI KU"

AINIYE awọn enia mbẹ loni ti nwọn ko ronu igbe-aiye wọn. Nigbagbogbo ti a ba ti mba wọn sọrọ nipa ti Ọlọrun ni nwọn ma nfun wa ni idahun pe, "Kini o ku mi ku, mo ti nlọ si Ṣọọṣi mo si ti nhu iwa rere si awọn ọrẹ mi ati si awọn enia gbogbo ti o ku." Lai mọ pe ohun ti o ku lehin mẹfa ju meje lọ, ati pe oh un pupọ ni o ku lẹhin ti awọn ko ti i ṣe.

Ẹ ma ṣe ma a ṣogo ninu awọn ohun asan aiye yi. Ọpọ awọn enia ni nwọn ti nfi awọn iṣẹ wọn ti nwọn ṣe ninu ara ṣe ogo niwaju awọn ẹlomiran pe awọn ti ṣe orişirişi nkan ṣohun ati sihin, ti nwọn ko mọ pe asan ni o ja si. Nwọn ro pe nigbati awọn ko ti şişẹ ni ọjọ ọsẹ ti awọn si nlọ si ṣoọşi nigbana ohun gbogbo ti bọ si i, awọn si ti di onigbagbọ tooto.

### AKISA ẸLẸGBIN

Awọn miran ẹwẹ si ro pe nigbati awọn ti nṣe ohun gbogbo ti o tọ si ọmọnikeji wọn, ti nwọn ko ba ẹnikẹni ja nitorina awọn ti di ẹni mimọ niwaju Ọlọrun. Njẹ eyi jẹ ohun kan pataki niwaju Ọlọrun bi, lai gba Jesu Kristi Ọmọ Rẹ gbọ? "Gbogbo wa si dabi ohun aimọ, gbogbo ododo wa si dabi akisa ẹlẹgbin . . ." (Isaiah 64: 6).

Ọpọ awọn enia ti nwọn ti jẹ, ti nwọn si ti yo ninu aiye yi ni nwọn ma nro ninu ara wọn nigbamiran pe kinni o ku ti awọn iba şe, tabi kinni o tun ku awọn ku ninu aiye yi, lẹhin ti awọn ti di olowo ti awọn si ti di onipo nla, ṣugbọn asan ni eyi jẹ lai si Kristi nibẹ. Nitotọ ni nwọn ngbe ibi giga, nwọn si ni awọn ohun ti aiye yi, ṣugbọn o ku ohun nla kan fun wọn ti Iṣe Jesu Kristi.

Njẹ a ha tun ranti ọkunrin ọlọrọ ti a ka itan rẹ ninu Bibeli ti o ni orişirişi awọn ohun ọsin ati awọn ohun alumoni aiye yi ṣugbọn o ku Kristi fun un ki o gba sinu ọkan rẹ ki o si şe alakoso ile rẹ?

### KO NI KRISTI

Ọkunrin ọlọrọ na ni awọn nkan ni anito ati aniṣeku ṣugbọn o ku Kristi ti ko ti i si ninu ile rẹ ti ko si ti i fun l'aye lati şe akoso ọkan rẹ. Bi ọkan rẹ tilẹ ma nyọ nigbamiran fun awọn nkan ti o ni ibanujẹ pọ ju ayọ rẹ lọ nitoriti ko ni Kristi nibẹ. O bere lọwọ ara rẹ ni ọjọ kan pe kinni o ku fun on lati ni ti on ko ti i ni, o ni kosi a si ri i pe ni oru ọjọ na ni Ọlọrun gba ẹmi rẹ lọwọ rẹ nitoripe o hu iwa aşiwere.

Njẹ iwọ na ni ohun ti o ku ọ ku loni bi ninu ọkan rẹ ti iwọ ko ti ni? Nitotọ gbogbo awọn enia ni o mọ ọ ni olokiki ati onipo giga, bẹni o si ti ni orişirişi awọn nkan ti o nfẹ, ohun gbogbo si ti tẹ ọ lọrun, ṣugbọn o ku kinni kan fun ọ lati ni ohun na ni Jesu Kristi ẹniti o le tun igbe-aiye rẹ şe fun ọ, lai si ibanujẹ ati wahala.

Iwọ ti o jẹ pe onitara enia ni o nşe si ọmọnikeji rẹ nipa ore şişe ati nipa ibanikẹdun, ti o si nfi gbogbo agbara rẹ şişẹ ti ara ti o si ro pe ko si ohun kan ti o tun ku fun ọ mọ. Kristi npe ọ loni, O si nsọ fun ọ pe o ku iye ainipẹkun fun ọ lati ni ninu igbe-aiye rẹ.

> "... Nitotọ ni nwọn ngbe ibi giga, nwọn si ni awọn ohun ti aiye yi, ṣugbọn o ku ohun nla kan fun wọn ti I ṣe Jesu Kristi."

### IYE AINIPẸKUN

Ẹlẹṣẹ ni ọ, Jesu si nilati mu ẹṣẹ rẹ kuro ki o to le de ọrun alafia, "Gbogbo enia li o sa ti ṣẹ, ti nwọn si kuna ogo Ọlọrun" (Romu 3: 23).

Nitori On ni ẹnikanşoşo na nipa eyi ti iwọ şe le ri alafia fun igbe-aiye rẹ ati lati lọ sinu iye ainipẹkun lọdọ Ọlọrun. Ṣugbọn iwọ nilati gba A gbọ ki o si jẹwọ Rẹ niwaju awọn enia, nigbana ni yio mu ibanujẹ rẹ kuro. Nitori owo ko le tan ibanujẹ rẹ, bẹni ọrọ ko sile mu aro rẹ kuro, ṣugbon Jesu Kristi nikan ni o le mu gbogbo awọn nkan wọnyi kuro fun ọ ti yio si dari gbogbo ẹṣẹ rẹ ji ọ, yio si fi ayọ dipo rẹ fun o.

Nitori gbigba Jesu sinu ọkan rẹ ni ohun ti o tobi julọ ti o ku ninu igbe-aiye rẹ. Ọrọ Ọlọrun sọ fun wa pe ki a ko gbogbo aniyan wa le e lọwọ yio si tọju rẹ fun wa. "Ẹ ma a ko gbogbo aniyan nyin le e; nitoriti On nşe aniyan nyin" (I Peteru 5: 7).


## Ki ọpa-ẹhin le tọ-rọrọ ki tapa-titan si lagbara dada FUN ỌMỌ RẸ NI






# OSTERMILK

Ile işẹ egbogi Glaxo Laboratories Ltd., Greenford, England ni [illegible]

Awọn alagbata rẹ ni GLAXO-ALLENBURYS (NIGERIA) LTD. P.M.B. 2310, Lagos ati pẹlu ni ABA ati KANO


## ALAPARA

(Lati oju ewe keje)

tun rẹrin, O si mba iṣẹ rẹ lọ. Awọn ti nwọn jẹ ara ilu na wa nsọ fun wa pe ole ko ri aiye wa, ko si ri aye ni Lomẹ gẹgẹbi ti ilu wa. O ni bi awọn enia ba ja, ti nwọn ba si ko nwọn wa si tẹşonnu awọn, awọn onija na ko ni fi arare lọ sile wọn. Awa bi lere pe bi ole ba ja, kinni nwọn nşe fun wọn? O lanu, o ni HA! O ni bi a ba ri bi nwọn ti nşe awọn ole si, ẹnu yio ya wa. Olotu, mo fẹ sare de ibikan, ngo tun ma sọ iyoku fun nyin pẹsẹpẹsẹ. O digba.

OLOTU: O digba, ngo ma şe ireti rẹ lọjọ miran.


## CLASSIFIED ADVERTISEMENT

Moki gbogoo ẹnyin ọmọ ilu yi, ti ngbe Ghana pe E ku abaja Odun ti okọja yi, asi dupẹ ti Ọlọrun fi ọdun titun yi tişe ekini han wa lẹhin Ominira wa Nigeria Ki Edumare jẹki ọdun na otu gbogbo wa lara o. Mosi tun kiyin ku ipalẹmọ ti ipade wa nila tao şe nilu BIBIANI pẹlu agbegbe rẹ ninu oşu (April, 1961) ki aşişe imura silẹ dada fun ipade na tişẹ ikini lẹhin Ominirawa, ka sẹ idawo dada, kasi yan enia pataki wa sinu ipade na Tiyin Adekọla Akowe.

# Gọngọ sọ nibi ipade Igbimọ Ijọba Ibilẹ Ọffa:

## Awọn ọmọ Ẹgbẹ Olomi binu jade

GONGO sọ nibi ipade awọn aṣoju Igbimọ Ijọba Ibilẹ Ọffa ti nwọn ṣe gbẹhin ni ilu Ọffa laipẹ yi lori ọrọ tani yio jẹ oye alaga igbimọ eto inawo. Rogbodiyan na bẹrẹ nigbati o ya lati yan alaga eto inawo na, ti o si jẹpe Ọlọla J. S. Ọlawọyin ni ibo mu fun alaga na.

Bi nwọn ti yan Ọlọla Ọlawọyin tan ni Ọgbẹni Ademọla Oguniyi, Olori Ẹgbẹ Alatako Igbimọ na ti i ṣe ọkan ninu awọn ọmọ Ẹgbẹ Olomi (NPC) ti nwọn jẹ aṣoju ninu Igbimọ na ba tara dide, o ni on ko fi ara mọ pe ki Ọlọla Ọlawọyin jẹ alaga igbimọ eto inawo, o ni on si nfẹ ki alaga igbimọ na yẹ ipade igbimọ eto inawo ti nwọn yio ṣe laipẹ yi si igbamiran.

Bi Ọgbẹni Ogunniyi ti sọ ọrọ rẹ tan ni Ọlọla Ọlawọyin ba dide, o si fi yẹ ipade pe ki i ṣe ẹtọ ki ẹnikẹni o ṣe atako ẹniti ọpọ ibo bati yan sibi eto kankan, bi oluwarẹ ba ti jẹ ẹniti o ba ti le ṣe iṣẹ ti nwọn yan an fun. Alaga Igbimọ na, Mallam Mustafa Keji, Olofa Ọffa ni on ri si alaye ti Ọlọla Ọlawọyin ṣe. Nwọn si nṣe ipade na lọ.

Ko pe pupọ ni awọn ọmọ Ẹgbẹ Olomi ti nwọn wa ninu Igbimọ Ijọba Ibilẹ na ba jade kuro nibi ipade na. Ki a ma a ri ni Alaga Igbimọ na pẹlu awọn marun ti nwọn yan sinu Igbimọ tun jade pẹlu.

Ṣugbọn eyi ko da ipade duro. Bi Alaga ti jade ni ile ni nwọn ba yan Alhaji Bakare Adeyẹmi ti i ṣe Gbakeji Alaga pe ki o ma a ba iṣẹ niṣo. Bi nwọn ti mba ipade na lọ ni Akọda kan wọle de, o si ni ki nwọn da ipade na duro. O bi Alhaji Adeyẹmi kinni ẹtọ rẹ lati maa ṣe ipade nigbati o ti ri i pe awọn aṣoju diẹ ti jade kuro nibi ipade na?

Ọlọla Ọlawọyin si da Akọda na lohun. O ni Alhaji Adeyẹmi ni ẹtọ lati maa ba eto ipade na lọ, nitori igba ti o ba ti jẹ pe iye awọn aṣoju ninu igbimọ na ti o tọ lati maa ba ipade na lọ si wa ni ijoko, ti nwọn ko kuro, ti iye wọn ko si din. Lẹhin alaye Ọlọla Ọlawọyin yi, ni Akọda na ba pẹhin da, awọn aṣoju si mba eto ipade wọn lọ.

## Majẹkodunmi bẹ awọn ọmọ-ogun to gbọgbẹ wo

KADUNA.

ỌLỌLA Dọkita M. A. Majẹkodunmi, Minisita ti ngmojuto eto Ologun ninu Apapọ Ijọba Naijiria, lọ ṣe abẹwo awọn mẹrin ninu ọmọ Ogun Naijiria ti wọn ṣeṣe ni Kongo ni Ile Iwosan awọn Ologun ni Kaduna ni Ọjọ Abamẹta ti i ṣe ọjọ kọkanla oṣu yi.

Ọlọla Dọkita na ba awọn ọmọ ogun na sọrọ, o si ba wọn ṣe awada pẹlu. O yẹ ọjẹ egbo wọn wo. Awọn ọmọ ogun na ni Joseph Mndsa, Mafiri Dong, Musa Kagoro ati Kamaru Ajimta.

Awọn onkawe iwe "Irohin Yoruba" yio ṣe iranti pe ninu oṣu kinni ọdun yi ni nwọn fi ọkọ ofurufu ko awọn ọmọ ogun to gbọgbẹ lati ilu Leopoldville ni Kongo wa si Naijiria. Mẹta ninu awọn ọmọ ogun na ti san, nwọn si ti kuro ni ile iwosan ni Kaduna. Oku awọn mẹrin ni ile iwosan na, nwọn wa ni itọju, ṣugbọn a gbọ pe ara wọn ti nya nisisiyi.


*Mimọṣẹ owọ laọ́ fi mọ̃!*

Ẹnito lè ṣiṣẹ owọ

ni yio mã gbowo to dara.

*O lé ni ẹ̀dẹ́gbẹta ara Nigeria*

ti a ti kọ́ niṣẹ owọ tabi ti asi

nkọ́ niṣẹ ni awọn ile ikọṣẹ lọdọ

THE UNITED AFRICA COMPANY

THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED


## Ẹgbẹ Afẹnifẹre Oke ọrẹ yan Oloye

OKE ỌRẸ LẸBA ỌTTA.

ESE gbogbo awọn ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre ẹka Oke Ọrẹ ni Agbẹgbe Ọtta, lo pe sibi ipade nla ti nwọn ṣe laipẹ yi nile ipade wọn: Ohun pataki ti nwọn ṣe lọjọ na ni eto ifinijoye.

Nwọn bẹrẹ ipade na pẹlu adura, lẹhinna ni nwọn wa ṣe eto ti oye. Awọn ti nwọn jẹ oye ati oye ti nwọn jẹ na ni wọnyi:

Oloye Michael Kumapani, baba ẹgbẹ; Oloye Tijani Ojẹ, baba isalẹ; Ọgbẹni Jimọh Akẹlẹmu otun baba ẹgbẹ; Ọgbẹni Buraimọh Lawal, osi baba ẹgbẹ; Ọgbẹni Lawal Ajibawo, aṣiwaju ẹgbẹ; Ọgbẹni James Fagbenro, alaga ẹgbẹ.

Iyaafin Abigael Ola-Olu, Iya ẹgbẹ; Abiola Gabriel, akapo; Julianah Ibiyemi, otun iya ẹgbẹ; Serah Olubiyi, otun iyalode.

Ninu awọn enia pataki-pataki to wa sibi ipade na ni Oloye Ẹkẹrin Ajegunlẹ, Baba Oje ti Ado-Odo; Ọgbẹni Samuel Laniba ti Igbela, ati Ọgbẹni Michael Olubiyi ti Oke Ọrẹ.

## Adajọ ṣe ikilọ fun awọn ọlọpa

ADAJỌ Kotu Ibilẹ ni Ikẹja, Ọgbẹni G. Adeogun, ṣe ikilọ fun awọn Ọlọpa gidigidi pe nwọn nilati maa mọ ẹjọ wọn dada ki nwọn to maa gbe wa siwaju kotu. O ṣe ikilọ yi nigbati o nṣe idajọ fun ọkunrin kan ti orukọ rẹ njẹ Jimọ Ọtunimale ati obirin kan ti orukọ rẹ njẹ Sẹlina.

Awọn Ọlọpa mu awọn mejeji yi wa si kotu fun pe nwọn nṣe ibalopọ pẹlu ara wọn lalai ki iṣe tọkọ-taya. Nigbati Adajọ bere lọwọ wọn pe nwọn jẹbi tabi nwọn ko jẹbi, nwọn ni awọn ko jẹbi ẹsun ti Ọlọpa fi awọn sun si kotu.

Ẹjọ ti awọn Ọlọpa ro nipe Sẹlina pẹlu ọkọ rẹ ti ja, eyi si mu ki o kuro nile ọkọ rẹ na lọ si ile Jimọh ni Abule Isheri-Olofin laipẹ yi. Nwọn ni kotu ti ya Sẹlina pẹlu ọkọ rẹ na sọtọ.

Ẹjọ ti Jimọ ro niwaju Adajọ nipe on ko tilẹ mọ Sẹlina ri, a fi igbati awọn jọ pade ni kotu lọjọ na. Ninu ẹjọ Sẹlina paapa, o ni on ko tilẹ ri Jimọ ri rara, ki o to to ọjọ ti awọn wa si kotu niwaju Adajọ yi. O ni igbati on pẹlu ọkọ on ja, ọdọ ẹgbọn on kan ti orukọ rẹ njẹ Adeyẹmi Peters ni on ngbe ni Odi-Olowo, Mushin.

Ninu idajọ rẹ, Ọgbẹni Adeogun sọ pe igbọnwọ ni awọn Ọlọpa mu Jimọ ati Sẹlina wa siwaju on. O ni awọn ẹlẹri Ijọba ko sọ ninu ẹri wọn pe awọn ri Sẹlina ninu ile Jimọ. O ni nisisiyi ọrọ na wa dabi igbati enia ngmefo lasan ni. O ni nitorina, on da awọn mejeji silẹ, ki wọn maa lọ ni alafia.


## Ran awọn eree lọwọ Da ẹhin didun duro

Ara rẹ nwẹ omi-aisan, kokoro-arun ati pantu oloro jade kuro ninu ẹjẹ rẹ lati ino adọta-le-ẹgbẹrinwọ ihọ kereke tabi awọn asẹ ti o wa ninu Eree (kidney) rẹ. Bi awọn ọrọ ti o wa ninu awọn Eree (kidney) tabi Apọ-itọ rẹ ba nfi iya jẹ o nipasẹ ito rukureku, "TI O SI NTAFẸ LORU LORU TI LAKU-REGBE" nyọ ọ lẹnu, ti bebe isalẹ-ọja rẹ ba wule, ẹhin didun ti gbogbo igba ara ba nro ọ tabi ti ko ba dun ọ nidi, bere si i ran Eree ino rẹ lọwọ nipa ino CYSTEX loni. CYSTEX a ma a ṣe iṣẹ lẹhin wakati mẹta kiakia ni yio si wọ gbogbo irora rẹ san ti yio si mu ọ lara da, a ṣeleri lati da owo rẹ pada ti ko ba ri bẹ ẹ. Bi apoogun rẹ lere.

**Cystex** CYSTEX loni

fun Eree (kidney), Lakuregbe, Ile-Itọ

